**Lakaye Oro**

Pupọ ninu awọn ọdọmọkunrin, ti ko ni epinni aladojọ lọwọ, ti nwọn nba ọmọlọmọ lori jẹ kiri nwọn ko le ṣaifi ori gba epe, ti o nsọ wọn di alaini lari.

Iku arun lo npa wọn, Enia buruku ki yio lọ laijiya, ma ṣe jẹki nwọn fi ẹgan ba aiye rẹ jẹ. Ẹlẹtan pọ larin wọn.

EKU AJODUN OMINIRA NAIJIRIA

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

**Owe**

Gbẹdogbẹdọ ko le gb'agogo, Alọ'lẹkẹ ko le lọ baba, alagbẹdẹ ko le rọ ojugun, akoko ni awọn le gbẹdo, ọpọlọ ni awọn le lọ lẹkẹ.

Awunrebe ni awọn le hun aṣọ, talo jẹ fi odo Akoko gun iyan, tani jẹ so lẹkẹ ọpọlọ mọ ọmọ rẹ lọrun, tani jẹ fi aṣọ awurebe bora.

VOL. V No. 302 MONDAY OCTOBER 2 — OCTOBER 9 1961 KỌBỌ MEJI (2d)

# Ọmọ oku Ọrun kan ṣegbe sinu Ina nla ti o jo l'ebute Ijẹ

OBALENDE: — Nse ni ẹsẹ nṣe giri-giri lọna adugbo Ọbalende n'lu Eko, ti o ni mọto ko jẹki a mọ o ni kẹkẹ, ti Panapana ko jẹki a mọ awọn Ọlọpa, ti awọn ọmọ Scouts ko jẹki a mọ Brigade, ti Ambulansi ko jẹki a mọ awọn Alagbelebu nigbati Ina nla kan fi bẹrẹ si jo ni Ebute Ijẹ ni Ọbalende

Awọn ile ti a gbọ wipe o jona lọjọ na le ni ọgọrin ile ati nigbati ina na relẹ tan, iye awọn enia ti ko ri ile gbe to adọjọlelẹgbẹrun enia, ninu jamba ina yi ni ọmọ kekere kan ti ko ju ọmọ ọdun marun lọ ti oruko rẹ njẹ Fatayi Tawaliyu jona sinu ile, nibiti o gbe sun si.

A gbọ wipe lọdunni ni ọmọ na dagba to ẹniti o nlọ si ile iwe, lẹnu ọjọ mẹta yi ni Iya ọmọ na salaisi, ẹru na wa di ẹru ti Baba rẹ nikan, ṣugbọn lọjọ buruku yi, Tawaliyu ti ise baba ọmọ na wa ninu amọdi to bẹ ti wọn ni lati gbe lọ si ile Alaisan.



AWỌN TI A NWO NINU AWORAN YI NI, AWỌN TI INA JO DUKIYA RẸ, TI WỌN TUN NFI IGI TANLẸWO, BOYA WỌN LE RI LARA NKAN WỌN TI KO JONA TAN

Nigbati ina na ṣẹlẹ, ninu ile ni ọmọ na sun si, nigbati olukuluku nsa asala fun ẹmi rẹ, oju orun ni ọmọ na wa titi ina fi jo pa. Iye dukia ti o padanu fẹrẹ to ẹgbata pọun, die ninu awọn ti o sofo ni, Iyafin Comfort Ọnajole, Lamidi Amos, ati Salawu Alaba, O. J. Okoro

## Femi Pearse di ologbe

LONDON:– Anuṣeni gidigidi lati jihin iku Dokita Fẹmi Pearse tiṣe ọkan ninu ọmọ bibi ologbe S.H Pears onile Elerin nla ni Oke Ologbowo

A gbọ wipe ẹni ọdun marun-diladọrin ni Dokita yi ki o to fi ile aiye silẹ, ati wipe, o ti kuro lẹnu iṣẹ ọba, Laipẹ yi ni a gbọ wipe o dakan lọ silu Oyinbo ki ọlọjọ to de si ni ọhun.

Oṣe! ki a to ri ẹran bi erin, odigbo ki a to ri ẹran bi ẹfọn, o di ọdan, ki ato ri ẹiyẹ bi ọkin, o di kese. Sunre.

**Awa Osise Iwe Irohin Imole ki** gbogbo awọn ara ilẹ Naijiria pe, ẹ ku ajọdun Ominira ilẹ wa ki ọpọ rẹ ṣoju ẹmi wa o. Amin.

# Ọrọ Olotu

## Ominira ti di Itan fun Enia Ile Naijiria

Ni ana ti aṣe ọjọ Aiku lo pe ọdun kan ti Naijiria gba Ominira, ati ti o ti bọ lọwọ Ajaga oko Ẹru ti o ti wa lati bi iwọn Ọgọrun ọdun sẹhin labẹ Gẹsi. Eleyi jẹ ohun ayọ, bakanna lo jẹ ohun ti a gbọdọ ronu le lori nitotọ Naijiria ti gba Ominira lọjọ kini osu kẹwa ọdun to kọja (1st October 1960.) o si ti di Ilu titun ati pe lagbara Ọlọrun Ọ b a to l'aiye to l'ọrun ko ni jẹki Naijiria pada si oko Ẹru mọ.

Ohun ti o wa yẹ ki gbogbo wa ma ro nipe, ọna wo ni a o gba ti a o fi le mu Ilọsiwaju, Ifaiya balẹ ati alafia wa fun gbogbo enia Ilẹ Naijiria. Ko si idahun ti Irohin Imọlẹ ro wipe o yẹ, ju w i p e ki gbogbo wa laiye-kaye tabi Ipo-ki-po ti a ba wa, a gbọdọ sa ipa lati se iṣẹ sin Orilẹ-ede wa tọkan-tọkan, ati pe a gbọdọ wa ni irẹpọ, nitoripe ibiti irẹpọ ba wa, loni lati toro bi omi amu.

Ọpọlọpọ lo ni ero wipe, ti on ba ṣe iṣe sin Orilẹ-ede on, wipe adanu ni on pa ni. Eyi kise bẹ rara, nitoripe bi Iwọ ko ba jere iṣẹ rẹ, Ọmọ rẹ tabi ọkan ninu awọn ẹjẹ rẹ yio jẹ nibẹ, bakanna ni awọn kan lero pe, bi awọn ko ba fi tọkan-tọkan sin Orilẹ-ede, wọn, ko si ẹṣẹ nibẹ. Ẹṣẹ nla si Ọlọrun ati si enia patapata gba ni ki enia male fi tọkan-tọkan sin Orilẹ-ede rẹ. Owe kan lo sọ bayi wipe, ohun ti enia ba gbin ni yio ka, bakanna ni a ki gbin alubọsa ki o hu ẹfọ, ohun ti a ba gbin, ni a o ka.

Ọrọ na di ọwọ gbogbo awa e n i a Ilẹ Naijiria o, gbogbo wa lamọ pe, ninu aisọkan wa gẹgẹbi Orilẹ-ede Alafia ko le sọ kalẹ wa lati Ọrun ati pe nipa Isọkan ni Alafia ati Ire le fi to wa lọwọ.

Lagbara Ọlọrun Naijiria yio tun bọ di Ilu Olokiki ti gbogbo enia yio ma ga ọrun wo. Bi yio ti ṣe dara o wa lọwọ awa enia Ilẹ Naijiria.

IROHIN IMỌLẸ KI GBOGBO Ọ M Ọ NAIJIRIA KU ORIRE O, Ẹ KU Ọ D U N O. ỌLỌRUN JẸKI ỌPỌLỌPỌ RẸ BA WA LAIYE O.

# SE BOTIMO (APA 4)

LATI ỌWỌ:— FUNMILAYỌ KOFOWORỌLA

Nigbati ilẹ ọjọ keji mọ, Iranlọwọ de, awọn mejeji si nsun orun asunwọra, o si rọra ji wọn pẹpẹpẹ, o ni ẹ ku owurọ o, ẹnyin ara ẹ ku arẹ, ẹ ku iṣẹ owo, alafia ha kọ lẹ ji bi? Ara le t a b i ko le.? Awọn mejeji ki i, nwọn si dọbalẹ gbọọrọ, nwọn ni o seun ana o, Oluwa yio san ọ ni ẹsan rere o, o ni Amin ati ẹnyin na pẹlu.

### IRANLỌWỌ NI BAWO NI WỌN TI RO ỌRỌ ANA SI.

Iranlọwọ ni ọrọ ti mo ni ki ẹ jijọ ṣaṣaro lori rẹ lana, kini ẹ ti ro si.? Koiti bere tan ti Nini-owo-ko-gboju-bọrọ ti da a lohun pe, bi o ba jẹ nipa ti ọna owo wiwa ni o, ko si ọna ti nko fi gba wa o, bi o kan ni ti ole jija, mo le ja ki nfi lowo, bi o jẹ wipe ti O ṣ o ṣiṣẹ ni, bi mo ba r'ẹni ṣẹ fun mi, nko kọ ki nwọna lọrun ki nsa ti l'owo ni ile Aiye, ki nwa ni yọtọmi, ki awọn orekelẹwa awe ọrun, ẹlẹyinju-ẹgẹ sa ti pa gbo yi mi ka, ki nsi ma jẹun to gbadun, ki nsi ma fi Ọti to dara le lori laṣiko. Ni temi o, Iranlọwọ, ti o ba juwe ọna eṣu fun mi, ibẹ ni ngo doriko, ngo si ma sin t i t i di ọjọ iku mi.

Iranlọwọ si bi l e r e ni gbolohun kan pe, njẹ o mọ igbẹhin eṣu, o ni on mọ dada, o tun bi lere pe, o fẹ ki igbihin rẹ ri bẹ ẹ? o ni on ko kọ, ki on ṣa ti lowo O TUN BERE LỌWỌ SEBOTIMỌ, o ni ewo ni Iwọ wi o? Ṣebotimọ ni aro o baba, ọna t'emi ko gba ibiti ekeji mi wi lọ rara, ọrọ Ọ l ọ r u n sọ bayi pe, Ibukun Oluwa ni i mu ni la ti ki i si fi la ala pẹlu rẹ, bi Iyawọ ko ba ṣe e fẹ, ngo jawọ k u r o ninu rẹ ni temi, nitoripe nko le sin eṣu rara, o tilẹ ti su mi, o gọ mi patapata, Iranlọwọ dakun fi ọna ti ngo gba han mi, ki mba le pada si ile.

Iranlọwọ ni, o ti wọ, o ti wọ ọ na, ngo fi ọna han ọ ṣugbọn osu mẹta oni, Iwọ ki yio fi oju ganni Ilu rẹ, ọrọ rẹ wọ mi leti pupọ, mo si tun ri ọgbọn kọ nibẹ, o ko ni ṣa iri owo mu rele, Iwọ yio jẹ pasapasa iya lọ na ti ngo f'ẹsẹ rẹ le na, ṣugbọn ma mu mọra, igbẹhin rẹ yio dara. Ṣebotimọ mi kanlẹ hẹ, o ni on gbọ.

### IRANLỌWỌ TUN DOJUKỌ NINI-OWO-KOGBOJU-BỌRỌ, O NI O WI ỌRỌ YẸN, ABI O ṢEṢI BỌ NI?

Nini-owo-ko-gboju-bọrọ ni Baba lati ọkan mi ni o ti wa, a ni mo nfẹ owo ni ọnakọna, nko si kọ ibiyiowu to le jasi. Iranlọwọ pe awọn mejeji papọ, o ni mo ṣe eyiti o tọ ati eyiti o yẹ ki nṣe fun nyin gẹgẹbi orukọ mi, ṣugbọn o ku si ọwọ nyin o.

Bi o ti nsọrọ lọwọ ni A r ẹ w a obinrin kan yọ lọkan tiẹn, ko ju iṣẹju mẹwa lọ ti o fi de ọdọ wọn. Ọkunrin Arugbo kan tun yọ ni odi keji, ko to iṣẹju mẹwa bakanna, o tun ti de ọdọ wọn. Ni Iranlọwọ ba fa Ṣebotimọ le Ọkunrin Arugbo na lọwọ, o si fa Nini-owo-ko-gboju-bọrọ le obinrin Arẹwa na l ọ w ọ, o si da gbere fun wọn pe, o digba o ṣe o.

Akiyesi:- Ẹ o ma ka apa karun lọsẹ to mbọ lagbara Ọlọrun, ki Ọlọrun Ọba ṣe itọju gbogbo wa o. Amin.

GBANGBA DEKUN!! KEDERE BEWO!!!




OLUBORI EGBOGI "IKỌ"

Bi Amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ọ lẹnu fun nkọn bi ọdun kan tabi jubẹ lọ, awọn egbogi rọbi-rọbi ko le se iwosan rọ rara, ma fi owo rẹ ṣe Ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni. "PORAL" ojulowo haunhaun, atamatase egbogi fun Ikọ here, Ikọ tutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaiya, Ikọ lile, Ikọ ti ọ ma mu enia tu kẹlẹbe nigbakugba lati inu "Ifun" wa (Lungs) tabi ti o ma nmu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan egbogi PORAL yi wo, Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia, Igbaaiya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro, "IKỌ" rọ yio si san patapata, iwọ yio ma jẹun daradara iwọ o si sun fọnfọn pelu Alafia de.

Bere egbogi yi ati awọn oriṣiriṣi egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBỌGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATA AIYERAIYE STREET, ADEỌYỌ IBADAN

## E ku Ajodun Ominira to ba wa L'ayo pelu Alafia

# Gbajumo ni Ololа Asikiwe nitorina ni Ipo Gomina Agba se to si

Ọlọla Dr. Nnamdi Asikiwe jẹ gbajumọ ti okiki rẹ si ti kan kakiri Ilẹ Agbaiye, nitorina ni Oye Gomina Agba ṣe tọ si, o jẹ ọkan ninu awọn enia pataki nilẹ Naijiria ti o ti njijakadi fun Ominira Ilẹ Naijiria, n i n u ẹgbẹ Dẹmọ eyiti Ologbe Herbert Macaulay da silẹ, on kanna ninu Ẹgbẹ Nigerian Youth Movement ati on kanna ninu N. C. N. C.



THE RIGHT DR. NNAMIDI AZIKIWE P. C.
(Gomina Apapo ile Naijiria)

Ọlọla Dokita Asikiwe ni momọ wipe, awa enia Dudu ti ni ọgbọn lori to lati ma ṣe Akoṣo ara wa, ọpọ ninu awọn enia gbagbọ pe, ohun ti Dr. Asikiwe nlepa yi ke le jẹ ohun ti yio ṣẹṣẹ, ṣugbọn ọrọ na di otitọ nisisiyi. Nigbati Ominira na si tẹ wa lọwọ, ki a to mọ ẹniti o yẹ fun Olori tabi Alaṣẹ Ominira. ohun ti a ni lati kọkọ ṣe ni pe ki a wa ẹniti iya jẹ pupọ nitori Ominira na lati fi ṣe Olori.

Lẹhin ti awọn ọjọgbọn ti joko papọ ronu le ọrọ na lori, ẹniti nwọn ri pe o yẹ fun Olori, ti okiki rẹ si kan kakiri Agbaiye ni Ọlọla Dr. Nnamdi Asikiwe Gomina Agba Apapọ Ilẹ Naijiria. Ọlọla Asikiwe sọ wipe, awọn ọmọ wa kekere ti o ṣẹṣẹ ndide, o yẹ ki nwọn kọ iṣẹ ni ṣiṣe, ni akoko yi ti a ṣẹṣẹ bẹrẹ Igba Ominira wa.


# Owo eni lafi ntun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, bi airọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọ ọ lẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ lo kọko bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MỌLẸYẸ STREET
P. O. BOX 166. YABA - NIGERIA


A ko gbọdọ fi ọrọ ẹnu wa ṣe Idina si isọkan Ilẹ Naijiria, nitoripe emi gbagbọ pe, Irẹpọ ati Isọkan yio fi ẹsẹ mulẹ larin wa.

Pẹlupẹlu diẹ n i n u awọn Akonijẹ Ijọ Kiriyo ko tẹle apẹrẹ J e s u nipa wipe ki nwọn ri ohun ti ko dara ki nwọn si pe ni aidara.


# E dinwo Oja fun ti ajoyo Ominira

Iwe Egbogi Ajẹbidan Agbabietu ti a ti nta ni (25/-) ri di (20/-). Iwe Ilana IFA, Iyanrin tite ati Etutu ṣiṣe ti a ti nta ni (20/-) ri di (15/-). TURARI I t a j a adu a Tetedamilohun ti a ti nta ni (10/6d) Pangolo, di (6/6d). Iwe ITUMỌ Ala ti a ti nta ni (2/6d) di (2/-). Iwe GBEDEGBẸYỌ Hausa ti a ti nta ni (3/-) ri di (2/-)

Tete wa ra tirẹ l o n i, nitoripe awọn ọja yi yio tun pada di iye ti a nta wọn ni Monday ti o mbọ.

MANAGER.
6, Ojo Road. Oduabọrẹ
Mushin

BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMI REN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yọn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ransẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe, ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de ọkọn lọsan tabi loru, bi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara to E-emi (breath) inu ko ba gunlẹ daradara to nitoripe arẹ tabi wahala ṣiṣe to "NJẸ" fun awọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọdun lọ si oke de adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jolọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigbakugba "Arọ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu.

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

ADEDUN CHEMIST
4, WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878.

# AFIKUN FUN AJỌYỌ ỌDU

## Aworan Awon Alakoso ile Naijiria


T. O. S. BENSON


Zana Bukar Dipcharima


AJA WACHUKU


ALHADJI ABUBAKAR TAF


IBRAHIM WAZIRI


Dr. E. A. ESIN


OLU. AKINFỌSILẸ


INUA WADA


Joseph Modupẹ Johnson


F. S. Okotie-Eboh


ỌLỌLA ADETOKUNBỌ


SHEHU SHAGARI


MAITAM SULE


Mohammadu Ribadu

# ...UN KAN OMINIRA NAIJIRIA



...AWA BALEWA



JAJA WACHUKU



USMAN SARKI



M. T. MBU



HON. OLAREWAJU



...I ADEMOLA



R. A. NJOKU



DR. MAJEKODUNMI



MUSA YAR ADUA



OBA ADENIJI ADELE

## Otito lo nmu ki ilu ati Enia ni ilosiwaju

LATI QWQ:— LATIFU B. BABALQLA
Oludasilẹ ati Akọwe Agba Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

MO KI GBOGBO ẸNYIN Ọmọ ilẹ Naijiria, E ku ọdun, eku iyedun, ẹ ku ajọ yọ Ominira wa to pe ọdun kan ti a gba lana Ọlọrun jeki a se ọpọlọpọ rẹ l a i y e. ka lo Ominira na pẹ, Ọlọrun ko ṣe lomi Idẹra fun wa, maṣe lomi Ioira fun wa Ọlọrun Ọba, yio tu ,yio ba, fun gbogbo wa. A o ri owo na, a o ri ọna gbe gba o. Ọrọ ti mo fẹ ba yin sọ lọsẹ yi ni nipa Otitọ.

Emi ko ri ohun k a n ti o ngbe Ilu ga ju Otitọ lọ, nitori rẹ ni mo ṣe fẹ sọrọ lori rẹ lọsẹ yi.: Kini Itumọ Otitọ? Itumọ ti emi ri si nipe, Otitọ jẹ ohun ti o mu ọ k a n enia fuyẹ, ti ko si njẹki enia papa bẹru loju Iku Otitọ jẹ Isura ti o ni Iyebiye, ti ko si owo ti o le raa, nitorina Otitọ jẹ ohun pataki ti o jẹ ohun Iyebiye.

Ẹ wo gbogbo Agbaiye loni, ragbaragba, rederede, rudurudu ni o ri, kilo fa a? Tabi ki ni ko jẹki ọkan ọmọ Araiye balẹ lode oni, nitoripe, Otitọ ti tan lori ilẹ aiye. Ti Otitọ ba wa bi ti aiye atijọ ni, Igbadun ni aiye ko ba jẹ, ṣugbọn bi o ti wu ki Otitọ kere to, Otitọ ni yio leke.

Ohun to fa ti a i y e ko ṣe ti parọ nipe, awọn Olotitọ diẹdiẹ yi wa ninu aiye, ṣugbọn o yẹ ki a yẹ ara wa wo, gbogbo nkan ti o nṣẹlẹ kakiri aiye fi han gbangba pe, o yẹ ki a yẹ ara wa wo. Enia melo lo nṣe iṣẹ ojọ rẹ gẹgẹbi iṣẹ? m e l o ninu wa to nṣe owo pẹlu Otitọ, tabi melo ninu awọn Alakoso lo nṣe iṣẹ Ijọba tọkantọkan? Kilo fa eleyi? Otitọ ti ko si mọ ni.

Iparun lede ba wa nigbakugba, boya lọwọ lọwọ yi, ti o nka Iwe mi yi ni, tabi boya ki ilẹ to su ni, boya lọla, ọtunla tabi lọdun ni. Ṣugbọn ọkan da mi loju pe, ti ko ba si Otitọ, aiye yi ko ni pẹ parun, ọrọ mi ti ọsẹ yi jẹ Iwasu, ṣugbọn emo mọ pe emi ki ṣe Alufa, ṣugbọn sibẹ gẹgẹbi mo ti jẹ akọwe Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye, mo ni latı ṣe iṣẹ itoni sọna.

### OYẸ, O SI TỌ, PE KIA YẸ ARA WA WO

Ilu ki lọla tabi lokiki ti ko ba si otitọ ninu rẹ, asan ni, ẹ ṣe ki a mura ki o t i t ọ leke bi otitọ ba leke nise ni aiye yi yio toro bi omu tutu, Iwa madaru, kodara, Agbere, Ole, Igara, Pansaga, Eke, Alọnilọwọgba ko dara, ko yẹ Ọmọ enia, gbogbo wa la jẹbi iwa yi, tabi ko jẹ bi rẹ, Olododo melo lo wa ninu wa?

Nitorina e jẹki otitọ leke ohun gbogbo ti a ba nṣe.

## Alo o, Alo!

Lati Qwọ:- Latifu Musari (Agege)
Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye No. 97

Nwọ ge l ri, nwọn bẹ nidi, o ni on ṣẹṣẹ bẹrẹ si jẹ aiye on ni, Kilo njẹ bẹ?
Idahun;- Apọnra
Ẹṣẹ ina bo si u omi ko ku. Kini o?
Idahun:- Ẹyin
Pẹtẹpẹtẹ Ọyọ ta sinu lẹrọkẹ ko le ṣi. Kini
Idahun:- Ila oju enia.

# Oloye Awolowo seleri odun meta lati fi tun Ibadan se

Nigbati Oloye Awolọwọ bọ dele lati ori irin ajo rẹ, o ṣeleri wipe larin ọ d u u mẹta ti o mbọ yi, on yio ṣe Iranlọwọ, ti Ilu Ibadan yio fi dara ni wiwo lati pe ni olu Ilu Ipinlẹ Iwọ Orun, o sọrọ yi nigbati o de Ibadan ti awọn ọmọ Ẹgbẹ Action Group wa nki pe o ku abọ o ku orire.



Nisisiyi ni a o ri aye lati yọ ọda soju ona mote, ti a o tunbọ kọ awọn Ile Ẹkọ Giga, ati Ile awọn Alabiyamọ tabi Ile Igbẹbi, ati ibiti a o ti ma gba egbogi fun Iwosan. O gba awọn I j ọ b a Ibilẹ niyanju, ki nwọn tunbọ mura si ilọsiwaju Ilu Ibadan, Ijọba si ti ṣe tan lati ṣe Iranlọwọ fun wọn. Oloye Awolọwọ k a n sara si awọn Ẹgbẹ obinrin nitori orire wọn ninu Ibo ti nwọn di kọja lọ yi.

Nwọn ṣe ileri pe, awọn yio ko iwa abẹtẹlẹ s i l ẹ ati iwa Ilara kẹta ati kenimani, Ọkanjuwa gbogbo silẹ awọn yio si ma wa ire ati Ilọsiwaju Ilu Ibadan.

---

## Benson fe lati lo agbara re fun ire ile Naijiria



T. O. S. BENSON

Ọgbẹni T. O. S. Benson ti fi ara rẹ jin pe on ni lati ri wipe ẹrọ Television ti a ma nri ni alalẹ ki gbogbo rẹ si jẹ ọkanna papọ pẹlu ti ilu Eko, ko maṣe si pe, ọkan tilẹ Hausa, ọkan tilẹ Yoruba ati ọkan tilẹ Ibo, ṣugbọn ki o jẹ pe, eyiti a ba nwo ni Eko na ni a o ma wo ni ibikibi ni Naijiria.

Eyi yio bẹrẹ nilu Eko ni bẹrẹ oṣu April ọdun 1962. Ọgbẹni Benson si ti tọ wọ bọ we adehun fun awọn Onişowo ara ilẹ Amẹrika meji orukọ wọn ni wọnyi R. W. Sarnoff, ti iṣe Alaga B N. B.C (Board of National Broadcasting Corporation), tilẹ Amerika ati Ọgbẹni Alfread Stern Alaga ti National Broadcasting Comapny

Ile ibiti nwọn ma gbe kọ ile ẹrọ na si wa ni O k u n Alagia.

IKI NI FUN NIGERIA, FUN AJỌDUN OMINIRA

## Awa o ma yo b'odun ijubili wa ba de̩o, awa o ma yo




Nigba lailai bi akoko ajọdun ba mbọ bayi, ni iwọ yio ma gbọ orişirişi orin lẹnu awọn Kiriyo. Ọkan ninu awọn orin ti a ngbọna ni orin ti a fi'şe ẹsin ọrọ iwe oke yi.

Awa ara ilẹ Naijiria, ti Ọlọrun ṣe logo, ti o gbe Ominira le wa lọwọ, e jẹki a fi ẹsọ jaiye, kişe ohun atata lati ma fi ọla wa şe igberaga si awọn aşiwaju wa, tabi ki a fi wọn fẹla.

Awọn asiwaju wa ni baba wa, bi a tilẹ nşe idara si ipo ti Ọlọrun fi wọn si nitori owo nlanla ti nwọn ngba, iwọ sa nireti, ki o si mu şuru nitoripe agba ti o ni suru, ohun gbogbo lo ni.

Olotu Iwe Irohin Imọlẹ ki gbogbo awọn aşoju wa, Ọkọwe wa, awọn Onkawe wa, ati gbogbo Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye, wipe, ẹku ọdun, ẹkuyedun ki Ọlọrun jẹki ajọdun Ominira bayi şe oju ẹmi wa. pẹ Amin Amin.

---

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI A NPE NI :-

"UROXAL"

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney - Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile itọ itọ-jijo enia, itọ riru, rukuruku Pipọn tabi rirun, lakuregbe, Ibaradi wiwo, orunkun, ọwọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.

Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkon tabi kiakia, didaji loru nigbakugba, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kia kia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina şọra ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ, maşe gba rara o!



Owo rẹ jẹ Şile Mẹfa abọ 6/ 6d owo ọkọ sile meji abọ (2/-6d)

Bere Egbogi yi ni Şọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ATI NI WỌN ŞỌBU IBADAN:-
IŞẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA IBADAN.

ADEBOGUN PATENT MEDICINE STORES.
APATAAIYERIYE STREET, ADEỌYỌ IBADAN

# KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jeri wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, Awa na nlo ni Ilu Gold Coast (A n k a r a) Ghana pẹlu, meji rẹ kosi ninu gbogbo orişirişi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




## Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹna si ni ẹwẹ ni Igboro Ilu Eko, irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia, tọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si nfi şe ọrọ ati orin kọ larin ara wọn jẹ nipa ti Egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni Leopills·

Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti wọn şe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JẸDIJẸDI bi o ti wu ki ọjọ rẹ le pọ to bẹna si ni awọn tun le fi ọwọ sọ aya tabi şe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi aisan bi Akọ Inarun, Lakuregbe, Ẹjẹ dudu lara, Arun Ẹdọki, Iju Igbẹsise, tabi Aikori Igbọnsẹ dede, Inuririn nigbakugba Ara-wiwo, Ẹsanri, Ehin didun, Oju sisan, tabi Aiko rira kedere K o k o r o buruku lara, Osi inu Onigbameji, ati orişirişi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" wọn yio ri alafia ni kiakia ti owọn ba nlo egbogi "LEOPILLS" nitoripe a si tun ma tun ẹjẹ şe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata.

ŞE IRATI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ
IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

Egbogi Leopills:- Igo nla Şile mẹfa pere ni.
Igo kekere:- Şile mẹta abọ pere ni.

Bere ojulowo Egbogi omiran fun orişirişi amodi ti o ba fẹ ni Şọbu awọn:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palm Church Street, P. O. Box 333 Lagos Nigeria Phone: 22878.** ati pẹlu ni Şọbu arabinrin Mrs. C. O. Babajide near Health Office Ibadan ati ni Ab i m b ọ l a Medicine Stores B29 Okeşha Street, Ileşha Bisale Medicine Store British & Foreign Medicine (Dealer) S. W. 6/458 AGBOJO STREET, IBADAN, N.

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe şọbu ti wọn nta lo gbe ransẹ lọ ra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ẸRU lọ ta adamọdi tabi orişi omiran fun ọ o, maşe gba rara.


# Ogbeni John Kennedy Baba egbe Ile Amerika



John Kenedy

Ogbẹni yi lo fi imọran kan lelẹ fun gbogbo Oyinbo ti o ngbe agbegbe Ila orun titi yika lọ de iwọ rẹ wipe ki enikeni maşe tun rọ ohun I j a Ogun mọ, ogbe imọran na kalẹ niwaju ẹgbẹ Majẹobajẹ

O şọ wipe, ki nwọn wa enia pataki ti o nfon ti o ni ekanna ki nwọn gbe oluware si ipo akọwe agba nibiti ologbe Dag Hammesskjeld

John Kennedy yi lo şe iranlọwọ l a t i gbe awọn ọmọ ilẹ Amẹrika d i d e lati wa se işẹ Olukọ nilẹ Naijira.

Wo iyoku ni oju Ewe Kejọ.






# Ojetayo kekere Awo (Alagbo Offa) waja

ỌFFA:- Ni dede osan ọjọ Eti tise ọjọkẹtadinlogun oşu kẹsan ọdun yi ni iwọn nkan bi agogo mẹta osan ni igbe ẹkun ati ofo nla ta nile Oyebalogun nilu Ọffa.

A si bere kini ode ti ariwo yi fi bori mọlẹ bẹ? Alagba kan si da ni lohun o se Erin wo, Erin lọ, Ewo bi alagbra ti şu bu ti ohun Ija si segbe; ani Eni nla lọ si ajule ọrun, Kekere Awo lọ, Ajani ọkin

Nitotọ baba na gbo o si kun fun ojo, tobẹ ti a gbọ wipe ko si agba baba yi ni Ọffa ati agbegbe rẹ mọ rara bi ọ ti wu ki o ri, Iwọnyi ni oriki Baba na.

WO IYOKU LOJU EWE KẸJỌ


# KERE O! Akiyesi Pataki

**Antoin Tablets! Antoin Tablets!!**

Ẹnyin Abiyamọ lọkunrin ati lobinrin. Mo ba yin yọ Eku afojuba egbogi pataki ti a şe iwadi rẹ lati ọwọ awọn Ọjọgbọn Onişegun (Specialists) Ilu Oyinbo.

Fun awọn ajakalẹ arun wọnyi:-

IGBONA: Eyi Ajẹ run ti o sọpọ ni isişinyi papa ni arin awọn Ọmọde ati Agbalagba.

RI FIFỌ. TULU. LUKULUKU, OTUTU IGBA AIYA. ARA RIRO ati OTUTU ỌRẸREN pẹlu AKOKORO. Awọ danwo ajẹbina ni ogun yi. Irohin ko to afojuba.

Bere iwe ti ẹ o fi lo lọwọ ẹniti o ba ta Egbogi na fun yin. O daju hanwun. Ẹ o ri işẹ rẹ lẹhin işẹju mẹdogun ti ẹ lo. Bere lọwọ Onişegun adugbo rẹ.

*Distributors:-*
HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES
26, Bishop Street Phone: 23457
LAGOS

# Awon ara Ile Amerika fi ara won jin lati ko Naijiria leko

OBẸRẸ LATI OJU EWE KEJE

Adọta enia ninu awọn ọmọ ilẹ Amerika ti nwọn wulẹ finu fẹdọ fi ara wọn ji lati wa fi ọdun meji tabi mẹta kọ ọmọ ilẹ Naijiria lekọ ninu ile ẹkọ giga, University College Ibadan, ati University College of Nigeria nilu Nsukka. Awọn Oniwe Irohin bere wipe, ninu gbogbo awọn adọta enia ti o kọkọ fi ara wọn ji, ẹṣe ti ko fi si awọn enia dudu ara ilẹ Amẹrika nibẹ?

Nwọn dabun wipe, ninu awọn ọgọrun enia tio tun
mbọ wa kọ awọn ọmọ ile Naijir a li ẹkọ, awọn enia dudu yio wa ninu wọn, nitoripe gbogbo wọn na ni John Kennedy ṣe eto fun· Awọn miran ninu ajumọsọ wọn pọ pẹlu awọn Oniwe Irodin sọ wipe, awon ti ngburo ilẹ Naijiria lati gba ti nwọn ti mbẹ ni ewe ati orisiriṣi aworan ti nwọn nri mu ọkan wọn fa lati wa fi ọgbọn ori wọn kọ awọn enia dudu ki ọgbọn ati imọ gbogbo wa le jẹ ọkan.

## Nigerian Ports Authority

INVITATION TO TENDER

*RECLAMATION BARGE NO. 1*

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the Reclamation Barge No. 1 now lying at the Apapa Trot Moorings.

2. The above vessel may be inspected on application to the Marine Superintendent, Apapa Dockyard, between the hours of 8. a. m. to 12 noon and 2 p. m. to 4 p. m not later than Monday 9th. October, 1961.

3. Tenders should be enclosed in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL-Tenders FOR R. B. I." and should be addressed to the Secretary to the Authority Nigerian Ports Authority, Private Mail Bag 2588, Lagos, so as to reach him not later than Tuesday, 17th October, 1961.

4. The successful tenderer will be required to tow the vessel from her present mooring to a site outside the ports limits at his own expense with suitable craft approved by the Authority, within 21 days of acceptance of his tender. If however the successful Tenderer's yard is within the port limits a deposit of £200 will be required from the purchaser, and should any portion be left below high water mark, the deposit will be forfeited.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

*L. ADE. KUYINU*
*Ag. Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice No 627

25th September, 1961.


## Akiyesi Pataki

**Sengovan Tablets! Sengovan Tablets!!**
(EXTRA STRONG FOR AGED MEN.)

SENGOVAN Tablets:- Jẹ ajidewe fun awọn agbalagba ati ilera gẹgẹbi ọmọkunrin.

SENGOVAN: Jẹ ọkan pataki ti a ṣe iwadi ni ilu Okere ni ilẹ Jamani lẹwọ ọkan ninu awọn Ọjọgbọn oniṣegun Arẹmọ ti ilu Western Germany. Fun arẹ ara eniti ọjọ ori rẹ to Ogoji si Ọgọrun ọdun (40: 80 years)

SENGOVAN: Jẹ ogun ti o ti wa lọjọ pipẹ fun anfani awọn Agbalagba Ilu Jamani ki a to ṣe amuwa rẹ si ilu Naijiria. Ajẹbina ni ogun yi Irohin ko to afojuba.

Bere, wa ri lọwọ awọn Oniṣegun (Doctors) Naijiria tabi lọwọ Alagba wa Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES. 26. BISHOP STREET. LAGOS PHONE. 23745. DIRECTION: 1 to 2 Pils is sufficient for your constitution, if so, do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU.


# Ojetayo Kekere Awo (Alagbo Offa) waja

OBẸRẸ LATI OJU EWE KẸJỌ.

Ajadi Ọkin ọmọ Ọlafa mojo, ọmọ Ọlalomi, ẹmọ Iyeru-Ọkin ọlọffa ọmọ Lareko dọgba ọkan ko gbọdọ ju kan ọmọ bọkan ju bọkan ju lọ nkọ? Ọba ni ko wọn roro, Ajadi ọmọ, Ajibọla ọmọ Alele, Ajadi baba Adebayọ, Ajadi ọkọ Pupa yẹmi ọkọ Dudu yẹmi, ọkọ Gere, Kukuru bi iku, Alagbo ọfẹ, Abiwomọ saka, Ajadi A meku wu wọn gbe Ajadi a mare Ekun wa ọnọ se; Awọn Onibata re a si tun ma ki'baba na bayi; Tayọ, Alagbo Ọfe; Eṣu o ṣce nikan mọ; O wọnu Eiye, Igbo wọnu eiye k'eiye ku, O wọnu Eiye, E sunmẹhin; Enikan ki fọmọ Ọlọba sun mọ ẹkun, E sunmẹhin, o gboju l' ekun sọmọ ajẹ niko, Alagbo ọfẹ A bi wọmọ ṣakaṣaka.

Oriki Ajadi ko lakitan ibi enu kani mo, ni nwọn ki baba mọ; Ajadi Ojọtayọ k kere Awo, Ọrun rere o. Sunre: Sunre: Sunre: O darin na ko, O doju ala ka to ri iru O digbo: Ka to rẹ fọn o dọdan, Ka to rẹni bi Ajadi, O d'ọrun Alakeji Haba ma jọkun. Ajadi a ni ki o ma jekolo, Ohun ti ara Ọrun ba njẹ, ni ki o ma ba wọn jẹ, A bagbala ṣe L'ogun l'ogun a binulẹ ṣe lamilami. Kukuru bi iku A fun wọn L'Erin, Onitohun, ko jẹ gbagbe Baba mi Ajadi Ọkin

# Egbe Igbomina Parapo (A G) ti ile Omupo se ipade Nla

Ni ọjọ Sunday tiṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Ẹgbẹ Igbomina Parapọ to faramọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ti ilẹ Omupo ṣe ipade nla kan nilu Eko lori ohun gbogbo ti o nṣẹlẹ ni ilẹ Omupo papa julọ lori iwa ti ẹgbẹ Olomi (N. P. C.) nhu ninu Igbimọ Ijọba Ibilẹ Omupo.

Lẹhin igbati awọn Councilors ẹgbẹ Igbomina Parapọ ṣe alaye ohun buruku, Iwa Inakuna, Iwa apa, Ope, ati aimọfẹ si Ilọsiwaju ilẹ wọn, eyi ti ẹgbẹ Olomi nhu eyit o si mu awọn binu jade ninu ipade Igbimọ Ibilẹ ti wọn ninu oṣu July 29 1961.

Ipade nla ti ọjọ Sunday na faramọ iwa ti ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapọ ti Igbimọ Ibilẹ na nhu. Nwọn si fi aṣẹ si pe awọn ọmọ ẹgbẹ tinu Igbimọ na ko ti o nfi aimọ eto se akoso Ijọra Ibile na bayi Ipinnu ti wọn ṣe pada ninu ipade na, ọpọlọpọ Aṣoju lati awọn ilu wọnyi yi:- Ọkanle, Idali, Igberi, Basanyin, Amọdu Bayagan, Igbowu, Oke-Odu, Ọbaloyin, ati ọpọlọpọ ilu miran ni ilẹ Omupo pẹlu ọpọ'ọpọ Aṣoju Ẹgbẹ lati ilu Omupo.

Ninu Ipade na, Alaga Ipade na, Ọgbẹni J. A. Adebara kesi gbogbo ọmọ ẹgbẹ Igbomina Parapo lati muragiri, ki wọ si gba ile Omupo lọwọ awọn ẹgbẹ N. P. C. ti ko fẹ Idẹra ati Igbesi aiye alafia fun awọn enia Ibilẹ na.

## Ma a ka Irohin Imole losese


Printed and Published by MODUPẸ PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street Lagos, Phone 21985. Olotu E. A. Adeniji 51, Tojuoso Street Surulere YABA.

FUN OWO IROHIN IMỌLẸ ỌDUN KAN
EKO:- Ṣile Mẹjọ ati Kọbọ Mẹjọ (8/8d)
Ilu miran ni Naijiria ati Oke Okun:-
Ṣile mejila ati Kọbọ Mẹfa (12/6d)